**STRONG TOWER ACADEMY.**

**Ọ̀SẸ̀-KẸ́TA:**

**KÍLÁSÌ: J.S.S. 2.**

**OLÙKỌ́: AYA AJAYI**

**IṢẸ́: Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá.**

**ORÍ-Ọ̀RỌ̀: ÀPólà ọ̀rọ̀-orúkọ àti iṣẹ́ rẹ̀.**

**KÓKÓ-IṢẸ́:**

Àpólà ọ̀rọ̀ orúkọ lè jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ ẹyọ kan tàbí àkópọ̀ ọ̀rọ̀ – orúkọ.

Àwọn iṣẹ́ pàtàkì ni ọ̀rọ̀ – orúkọ ń se nínú gbolóhùn èdè Yorùbá. Ó lè ṣiṣẹ́ Òlùwà (subject) Àbọ̀(object) Atọ́kùn (preposition) àti ẹ̀yán(adjectif).

1. Iṣẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ́ ní ipò Olùwà: Olùwà ni olùṣe iṣẹ̀lẹ̀ inú gbólóhùn. Ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn ni olùṣe iṣẹ̀lẹ̀ máá ń wà. B.A.

**<u>Kọ́lá</u>** jẹun. ‘ Kọ́lá’ ni olùwà

**<u>Ọdẹ</u>** pa ẹran . ‘Ọdẹ’ ni olùwà.

**<u>Bọ́lá</u>** jẹ ọ̀gẹ̀dẹ̀ ‘ Bọ́lá’ ni olùwà.

**<u>Olú</u>** rí wa. ‘Olu’ ni olùwà.

2. Ọ̀rọ̀-orúkọ tó n ṣiṣẹ́ àbọ̀ fún ọ̀rọ̀-iṣe: Àbọ̀ ni ẹni tí a ṣe nǹkan sí nínú gbólóhùn, Ọ̀rọ̀-iṣe ni ọ̀rọ̀-orúkọ́ máa ń tẹ̀lé nínú gbólóhùn. B.A.

Olú ra **<u>ìwé</u>** ‘ìwé’ ni àbọ̀

Mó jẹ **<u>iyán</u>** ‘iyán’ ni àbọ̀

Olùkọ na **<u>Mojí</u>** ‘Mojí’ ni àbọ̀.

3. Ọ̀rọ̀-orúkọ tó n ṣiṣẹ́ àbọ̀ fún ọ̀rọ̀ atọ́kùn . B.A.

Olú lọ **<u>sí ọjà .</u>** ‘ si ọjà’ jẹ́ ọ̀rọ̀ atọ́kùn

Ṣeun wà **<u>ní ilé</u>** ‘ ni ile’ jẹ́ ọ̀rọ̀ atọ́kùn.

4. Ọ̀rọ̀-orúkọ tó ń ṣiṣẹ́ ẹ̀yán: Ẹ̀yí ni ọ̀rọ̀ –orúkọ tó n ṣiṣẹ́ ẹ̀yan fún ọ̀rọ̀-orúkọ olùwà. B.A.

Bàbá **<u>arúgbó</u>** dà? ‘arúgbó’ ni ẹ̀yán

Akọ̀wé **<u>owó</u>** ti dé  'owó' ni ẹ̀yan.

Olùkọ́ **<u>èdè Yorùbá</u>** ti ra ọkọ̀ tuntun. 'èdè Yorùbá' ni ẹ̀yán.

**<u>Iṣẹ́-Aṣetilewá: (Assignment)</u>**

1. Kọ àwọn iṣẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ Márùn-ún, Márùn-ún ní ipó olùwà, Àbọ̀ , Atọ́kùn àti Ẹ̀yán.

ÌGBÀ KEJÌ: (2nd Period)

IṢẸ́: Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá.

KÍLÁSÌ: J. S. S. 2.

ORÍ-Ọ̀RỌ̀: **<u>Ìgbàgbọ́ àti Èrò Yorùbá Nípa Òrìṣà</u>.(Yorùbá beliefs/relationship with other dieties)**

KÓKÓ-IṢẸ́

Gẹ́gẹ́ bi ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá. Àwọn Oriṣà ní àwọn ìbọ, ti àwọn Yorùbá gbà bíi Alárina, alágbàwí tàbí onígbọ̀wọ́ láàrín wọn àti Olódùmarè.

**Àwọn orìṣà ilẹ̀ Yorùbá àti ojúṣe wọn.**

**Orìṣà Ọbàtálá:** Ọbàtalá ni aṣáájú gbogbo àwọn Orìṣà. Òun ni wọn gbà bíi igbákeji Olodúmarè. Òun si ni Ẹlẹ́dàá kọ́kọ́ dá. Ọbàtálá ni yóò ni yóò mọ ojú, imú, ẹnu, etí àti ẹ̀yà ara yóòkù . Olódùmarè yóò wá mi èémí ìyè sí imú rẹ̀. Idi nìyí tí wọn fi kìí ní:' Àjàlá Alámọ̀ ti mọ orí' tàbí 'Alámọ̀ rere'.

Funfun ni gbogbo nnkan Ọbàtálá. Àwọn àwòrò àti olúsin rẹ̀ máa n wọ aṣọ funfun, ìlẹ̀kẹ̀ fúnfun àti bàtà fúnfun.. Ẹfun ni wọn n kun ojúbọ rẹ̀.

**Òrìṣà Ògun:** Òun ni o ní agbara lórí irin. Gbogbo iṣẹ́ ti a bá fi irin rọ jẹ́ ti ògún. Ògún ni o fi àdá rẹ̀ la ọ̀nà fún àwọn oriṣa yóókù nígbà tí wọn n bọ̀ láti ikọ̀lé ọ̀run wá si ayé. Ibẹ̀ ni wọn ti fi jẹ oyè Ọ̀ṣìnmọlẹ̀. Ìtan fi hàn pé ọdẹ ni ògún nígbà ayé rẹ̀.

**Òrìṣà Ṣàngó:** Ṣangó ni a tún ń pè ní Olùfiràn tí o jẹ́ ọba Aláàfin Ọyọ rí. Wọn gbagbọ̀ pé o loógùn ati agbára lorí òjò, àrá àti imọ̀nà-mọ́ná. Bi ṣàngo bá ń sọ̀rọ̀ iná a maá jáde ní ẹnu rẹ̀. Ṣàngó bínú pokùnso nídìí igi 'Àyàn' ní kòso. Àwọn Ìyàwo rẹ̀ ni Ọya, Ọ̀ṣun àti Ọbà. Ọya ìyàwó rẹ̀ wọlẹ̀ ni Irá, o di odò. Àwọn àwòrò rẹ̀ máa ń mú oṣé Ṣàngó lọ́wọ́. Ọkùnrin wọn máa n dirun bii obìnrin.

**Ifá/Ọ̀rúnmìlà:** Ọ̀rúnmìlà ni Olódùmarè fún ni ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye láti fi wá tún ayé ṣe. Ìdí nìyí ti wọn fi ń kìí ní : 'Akéré finú ṣọgbọ́n'. Wọ́n gbàgbọ́ pé o wà ní ọ̀dọ̀ Olódùmarè nígbà tí Ó ṣèpín àwọn ẹ̀dá. Èyí ni wọn ṣe n pèé ní 'Ẹlẹ́rìí-ìpín'. Nítorí o mọ gbogbo ohun tí yoo ṣẹlẹ̀ sí ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan níle ayé.

**Èṣù:** Èṣù ní ọlọ́pàá tàbí oníbodè. Gbogbo àwọn orìṣà ní wọ́n bẹ̀rù rẹ̀. Ọrúnmìlà nìkan ló jẹ ọ̀rẹ́ rẹ̀. Èṣù ló màa ń wá oúnjẹ fún àwọn òrìṣà yóókù, tó sì ń bá wọn ọ́n gbé ẹbọ. Àwọn Yorùbá ka Èṣù si 'Aṣe búburu ṣe rere'. Ìta gbangba tàbi ẹnu odi ìlú ni ojúbọ Èṣù máa ń wà.

**Egúngún:** Èyí fí ìgbàgbọ́ Yorùbá nínú ìgbe ayé miíran lẹ́yìn ikú hàn.

**STRONG TOWER ACADEMY.**

**Ọ̀SẸ̀: KẸTA**

**OLÙKỌ́: AYA ÀJÀYÍ.**

**<u>Iṣẹ́- Àṣetiléwá. (Assignment) J.S.S.2</u>**

1. Ta ni Èṣù gẹ́gẹ́ bí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá? Sọ àwọn iṣẹ́ rẹ̀?

2. Kí ni o mọ̀ nípa oríṣà wọ̀nyí ní ṣókíṣókí:

i. Ọbàtálá

ii. Ọ̀rúnmìlà.

iii. Ògún.